Islamhouse.com
المحتوى الإسلامي
مؤسسة الشيخ محمد بن صالح العثيمين الخيرية رحمه الله تعالى

# “Isọrọ perengede lori pipe Shariah ati ewu dida adadaalẹ”

**Agba aafa Muhammad ọmọ Salihu Al-Uthaymiin**
- May God have mercy on him -

الإبداع في كمال الشرع وخطر الابتداع- يوربا

# “Isọrọ perengede lori pipe Shariah ati ewu dida adadaalẹ”

Agba aafa Muhammad ọmọ Salihu Al-UthaymiinMay God have mercy on him

شركاء التنفيذ:

دار الإسلام جمعية الربوة رواد الترجمة المحتوى الإسلامي

يتاح طباعة هذا الإصدار ونشره بأي وسيلة مع الالتزام بالإشارة إلى المصدر وعدم التغيير في النص.


Telephone: +966114454900

ceo@rabwah.sa

P.O.BOX: 29465

RIYADH: 11557

www.islamhouse.com

Ni orukọ Ọlọhun, Ọba Ajọkẹ aye, Ọba Aṣakẹ ọrun.

Gbogbo ọpẹ ti Ọlọhun nii ṣe. A dupẹ fun Un, a tọrọ iranlọwọ Rẹ, a si wa aforijin Rẹ, a si tun tuuba lọ si ọdọ Rẹ. Bakan naa, a fi Ọlọhun wa iṣọ nibi aburu ẹmi wa ati aburu iṣe ọwọ wa. Dajudaju ẹnikẹni ti Ọlọhun ba ti tọ sọna ko si ẹni ti o le ṣi i lọna. Ẹnikẹni ti Ọlọhun ba si yọnda iṣina fun, ko si ẹni ti o le fọna mọ ọn.

Mo wa jẹri pe ko si ẹnikankan ti ijọsin ododo tọ si i ayaafi Ọlọhun Allah Ọkan soso ti ko ni orogun. Mo si jẹri pe dajudaju Anọbi Muhammad ẹru Rẹ ni, Ojiṣẹ Rẹ si ni pẹlu. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ju fi ọnaamọ ati ẹsin ododo ran an. O si jiṣẹ naa de ogongo. O tun pe iṣẹ ifọkantan ti Ọlọhun fi ṣọ ọ, o si sọ ọrọ imọran fun awa ijọ rẹ. O si jagun si oju ọna Ọlọhun gẹgẹ bi o ṣe tọ ati bi o ṣe yẹ titi ti o fi pada sọdọ Ọba rẹ.

O si fi awọn ijọ rẹ sori ọna to mọlẹ gboo ti ọsan rẹ ati oru rẹ jẹ bakan naa (nibi imọlẹ). Ko si ẹnikan ti yoo kuna lati tọ ọna naa ayaafi ẹni ti yoo parun. O ṣalaye si oju ọna yii gbogbo nkan ti awọn ijọ yii yio bukata si nibi gbogbo igbokegbodo wọn debi pe Abu Dharri - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - fi sọ wipeKoda Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ko fi ẹyẹ to nfi iyẹ apa rẹ mejeeji loju sanmọ silẹ lai

ṣalaye imọ fun wa nipa rẹ.Arakunrin kan ninu awọn ọṣẹbọ sọ fun Salman - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - wipe Anọbi yin ti kọ yin ni gbogbo nkan titi to fi dori ilana bi a ṣe nṣe igbọnsẹ! Salman nibẹẹ ni, o ti kọ fun wa lati doju kọ kiblah(ibudojukọ irun) ti a ba fẹ ṣe gaa tabi ẹyọ, ati lati ma lo okuta ti ko to mẹta lati fi ṣe imọra, ati lati maa fi ọwọ ọtun taaba ati lati maa fi igbọnsẹ awọn ẹranko to ti gbẹ tabi eegun ẹran taaba.Iwọ naa o maa ri i pe Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ti ṣalaye sinu Alukurani alapọnle gbogbo origun (ipilẹ) ẹsin ati awon ẹka rẹ. O ṣalaye imọ imọlọhun lọkan ati oniruuru(ipin) rẹ. Koda O ṣalaye awọn ẹkọ ijoko awujọ ati bi a ṣe maa ngba iyọnda ti a ba fẹ wọle ẹlomiran. Ọlọhun Allah sọ wipe:

﴿يَـٰٓأَيُّهَا ٱلَّذِينَ ءَامَنُوٓا۟ إِذَا قِيلَ لَكُمْ تَفَسَّحُوا۟ فِى ٱلْمَجَـٰلِسِ فَٱفْسَحُوا۟ يَفْسَحِ ٱللَّهُ لَكُمْ ... ﴿١١﴾﴾ [المجادلة: 11]

“Ẹyin ti ẹ gba Ọlọhun gbọ lododo nigba ti wọn ba sọ fun yin pe ki ẹ sun nibi awọn ibujoko awujọ yin, ẹ ri i pe ẹ sun, Ọlọhun naa yoo fi aaye gba ẹyin naa”(Suratul Mujaadalah :11)

Allah tun sọ pe:

﴿يَـٰٓأَيُّهَا ٱلَّذِينَ ءَامَنُواْ لَا تَدۡخُلُواْ بُيُوتًا غَيۡرَ بُيُوتِكُمۡ حَتَّىٰ تَسۡتَأۡنِسُواْ وَتُسَلِّمُواْ عَلَىٰٓ أَهۡلِهَاۚ ذَٰلِكُمۡ خَيۡرٞ لَّكُمۡ لَعَلَّكُمۡ تَذَكَّرُونَ ٢٧ فَإِن لَّمۡ تَجِدُواْ فِيهَآ أَحَدٗا فَلَا تَدۡخُلُوهَا حَتَّىٰ يُؤۡذَنَ لَكُمۡۖ وَإِن قِيلَ لَكُمُ ٱرۡجِعُواْ فَٱرۡجِعُواْۖ هُوَ أَزۡكَىٰ لَكُمۡۚ وَٱللَّهُ بِمَا تَعۡمَلُونَ عَلِيمٞ ٢٨﴾ [النور: 27–28]

“Ẹyin ti ẹ gbagbọ lododo ẹ o gbọdọ wọ ile ti kii ṣe tiyin ayaafi ki ẹ kọkọ gba iyọnda ki ẹ si salamọ si awọn araale naa, ṣiṣe eyi lo dara fun yin julọ ti waasi Ọlọhun ba nwulo fun yin. Ti ẹ ko ba ṣe akiyesi ẹnikẹni ninu ile naa, ẹ o gbọdọ wọle ayaafi ki wọn o yọnda fun yin, ti wọn ba si sọ fun yin pe ki ẹ pada ẹ gbọdọ pada ni, ṣiṣe eleyii lo mọ ti o si rẹwa fun yin. Dajudaju Ọlọhun ni imọ si gbogbo nkan ti ẹ nṣe”(Suratul Nuur :27-28.)

Koda to fi dori ẹkọ aṣọ wiwọ ati imura, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿وَٱلۡقَوَٰعِدُ مِنَ ٱلنِّسَآءِ ٱلَّٰتِي لَا يَرۡجُونَ نِكَاحٗا فَلَيۡسَ عَلَيۡهِنَّ جُنَاحٌ أَن يَضَعۡنَ ثِيَابَهُنَّ غَيۡرَ مُتَبَرِّجَٰتِۭ بِزِينَةٖۖ..٦٠﴾ [النور: 60]

“Ati awọn ti wọn ti kọja ọmọ bibi ninu awọn obinrin ti wọn ko ni ireti ọkọ fifẹ mọ, ko si ẹṣẹ fun wọn ti wọn ba bọ jalibaba wọn silẹ ṣugbọn lai nii maa polowo ọṣọ ara wọn....(Suratul Nuur: 60)

﴿يَـٰٓأَيُّهَا ٱلنَّبِيُّ قُل لِّأَزۡوَٰجِكَ وَبَنَاتِكَ وَنِسَآءِ ٱلۡمُؤۡمِنِينَ يُدۡنِينَ عَلَيۡهِنَّ مِن جَلَٰبِيبِهِنَّۚ ذَٰلِكَ أَدۡنَىٰٓ أَن يُعۡرَفۡنَ فَلَا يُؤۡذَيۡنَۗ وَكَانَ ٱللَّهُ غَفُورٗا رَّحِيمٗا ٥٩﴾ [الأحزاب: 59]

“Irẹ anọbi sọ fun awọn iyawo rẹ ati awọn ọmọbìnrin rẹ ati awọn obinrin awọn onigbagbọ ododo pe ki wọn maa wọ jalibaba wọn ki o maa balẹ, ṣiṣe bẹẹ lo fi sunmọ julọ ti awọn eniyan yoo fi da wọn mọ bakanna ti wọn o si ni maa yọ wọn lẹnu Ọlọhun ni Ọba Alaforijin Onikẹ”.{Suratul Ah’zaab: 59}“

﴿وَقُل لِّلۡمُؤۡمِنَٰتِ يَغۡضُضۡنَ مِنۡ أَبۡصَٰرِهِنَّ وَيَحۡفَظۡنَ فُرُوجَهُنَّ وَلَا يُبۡدِينَ زِينَتَهُنَّ إِلَّا مَا ظَهَرَ مِنۡهَا ٣١﴾ [النور: 31]

Wọn o si gbọdọ maa rin ni irin ti awọn eniyan yoo fi mọ ọṣọ ti wọn lo pamọ sara wọn”{suratul Nuur: 31.}

﴿...وَلَيۡسَ ٱلۡبِرُّ بِأَن تَأۡتُواْ ٱلۡبُيُوتَ مِن ظُهُورِهَا وَلَٰكِنَّ ٱلۡبِرَّ مَنِ ٱتَّقَىٰۗ وَأۡتُواْ ٱلۡبُيُوتَ مِنۡ أَبۡوَٰبِهَاۚ.. ١٨٩﴾ [البقرة: 189]

“Kii ṣe iwa oriyin ni ki ẹ maa gba ẹyinkule wọle bi ko ṣe wipe iṣẹẹre ni ẹni naa to ba npaya Ọlọhun, ki ẹ si maa ba ojuule wọle”(Suratul Bakorah: 189)

Eleyii ati awọn oriṣiriṣi ẹsẹ, alukurani lo nṣe afihan pe ẹsin Isilaamu yii jẹ ẹsin to kun, to si pe ti ko nilo afikun gẹgẹ bi ko ṣe lẹtọ ka ṣe adinku nkankan ninu rẹ. Nitori eyi ni Ọlọhun ṣe sọrọ ti O si nroyin Alukurani pe:

﴿وَنَزَّلۡنَا عَلَيۡكَ ٱلۡكِتَٰبَ تِبۡيَٰنٗا لِّكُلِّ شَيۡءٖ ...﴿٨٩﴾﴾ [النحل: 89]

“A ti sọ tira yii kalẹ fun ọ, ki o le jẹ alaye fun gbogbo nkan patapata"(Suratul Nahl : 89)

Ko wa si nkan naa ti awọn eniyan ni bukaata si ninu eto ọrun ati ti aye wọn ti Ọlọhun ko tii ṣalaye rẹ sinu tira Rẹ tii ṣe Alukurani, o le jẹ pẹlu ọrọ taara tabi ko si jẹ itọkasi, o le jẹ eyi ti a ri gbolohun rẹ tabi ki o si jẹ eyi taa gbọ ye (lati ara gbolohun)Ẹ̀yin ọmọ iya mi (ninu ẹsin) awọn eniyan kan maa ntu gbolohun Ọlọhun ti ọla Rẹ ga to sọ wipe:

﴿وَمَا مِن دَآبَّةٖ فِي ٱلۡأَرۡضِ وَلَا طَٰٓئِرٖ يَطِيرُ بِجَنَاحَيۡهِ إِلَّآ أُمَمٌ أَمۡثَالُكُمۚ مَّا فَرَّطۡنَا فِي
ٱلۡكِتَٰبِ مِن شَيۡءٖۚ ثُمَّ إِلَىٰ رَبِّهِمۡ يُحۡشَرُونَ ﴿٣٨﴾﴾ [الأنعام: 38]

“Ko si nkankan to nrin lori ilẹ tabi ẹyẹ to nfi apa rẹ mejeeji fo bi ko ṣe ijọ ni awọn naa bii ti yin, A ko ṣẹ kini Kankan ku ninu Tira naa laikọ”{Suratul An'am :38}

Awọn eeyan yii maa ntu abala“A ko ṣẹ kini Kankan ku ninu Tira naa laikọ”pe itumọ “Tira naa” ni Alukurani, ṣugbọn eyi to jẹ ododo ni aaye yii ni wipe itumọ " Tira naa” ni LAOHUL MAH’FUS. Ẹẹ wa ri ọrọ ti Alukurani ni tiẹ, Ọlọhun ti royin rẹ lọna to lagbara ju lilo odi-ọrọ lọ, oun naa ni bi Ọlọhun ṣe sọ pe:“A ti sọ tira yii kalẹ fun ọ, ki o le jẹ alaye fun gbogbo nkan patapata"Iroyin yii lagbara o si tun han ju“ A ko ṣẹ kini Kankan ku ninu Tira naa laikọ lẹyin naa ọdọ Oluwa wọn ni a o ko wọn jọ si” lọ.

O ṣe e ṣe ki ẹnikan o sọ pe nibo la ti le ri iye onka irun maraarun ojoojumọ ninu Alukuraani?

ati onka irun kọọkan ninu Alukurani?

Bawo ni yoo ṣe dun un gbọ leti wipe ao ri alaye nipa onka rakah irun kọọkan ninu Alukurani ti Ọlọhun si sọ pe:“A ti sọ tira yii kalẹ fun ọ, ki o le jẹ alaye fun gbogbo nkan patapata"Esi ọrọ yii ni wipe Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ fun wa ninu Tira Rẹ pe ninu nkan to jẹ ọranyan fun wa ni ki a maa gba nkan ti Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ba sọ fun wa ati nkan ti o ba ṣe apejuwe rẹ fun wa

﴿مَّن يُطِعِ ٱلرَّسُولَ فَقَدۡ أَطَاعَ ٱللَّهَۖ وَمَن تَوَلَّىٰ فَمَآ أَرۡسَلۡنَٰكَ عَلَيۡهِمۡ حَفِيظٗا ٨٠﴾ [النساء: 80]

.“Ẹnikẹni ti o ba ntẹle ojiṣẹ Ọlọhun, ẹni naa ti ntẹle Ọlọhun niyẹn. Ṣugbọn ẹnikẹni to ba gunri (ti ko tẹle Anọbi) ao ran ọ gẹgẹ bii oluṣọ lori wọn”.(Suratul Nisaa: 80)

﴿.. وَمَآ ءَاتَىٰكُمُ ٱلرَّسُولُ فَخُذُوهُ وَمَا نَهَىٰكُمۡ عَنۡهُ فَٱنتَهُواْۚ وَٱتَّقُواْ ٱللَّهَۖ إِنَّ ٱللَّهَ شَدِيدُ ٱلۡعِقَابِ ٧﴾ [الحشر: 7]

"Ati wipe, ẹ gba ohun ti ojiṣẹ ba mu wa fun yin, ohun ti o ba si kọ fun yin ẹ jina si i, ẹ bẹru Ọlọhun, dajudaju Ọlọhun ifi iya jẹni Rẹ o le koko"(Al'hash'r 7)

Ohun ti sunnah ba ṣe alaye rẹ, dajudaju Alukurani ti tọka si iru nkan bẹ; nitori pe sunnah ipin kan ni ninu ipin meji ti waayi (Imisi) ti Ọlọhun sọkalẹ fun ojiṣẹ Rẹ, ti O si fi mọ ọn pin si, gẹgẹbi Ọlọhun ṣe sọ pe:

﴿... وَأَنزَلَ ٱللَّهُ عَلَيۡكَ ٱلۡكِتَٰبَ وَٱلۡحِكۡمَةَ وَعَلَّمَكَ مَا لَمۡ تَكُن تَعۡلَمُۚ وَكَانَ فَضۡلُ ٱللَّهِ عَلَيۡكَ عَظِيمٗا ١١٣﴾ [النساء: 113]

Ati wipe Ọlọhun Allah sọ tira naa kalẹ fun ọ (Alukurani) ati ọgbọn ati pe O fi ohun ti o o mọ tẹlẹ mọ ọ, atipe ọla Ọlọhun lori rẹ tobi jọjọ”.(An-Nisaa' 113)

Ni idi eyi, ohun ti o ba ti wa ninu sunnah, o ti wa ninu Iwe Ọlọhun Allah Ọba Abiyi julọ, ati Ọba ti O gbọn-n-gbọn.

Ẹyin ọmọ iya ẹsin, ti eleyi ba ti fidi mulẹ lọdọ yin, nje Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - wa papoda bi, ti nkankan si ṣẹku ninu ohun ti o le mu eyan sunmọ Ọlọhun Ọba Aleke Ọla ninu ẹsin ti ko si ṣe alaye rẹ?

Laye laye Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe alaye gbogbo ẹsin, yala pẹlu ọrọ ẹnu rẹ ni, abi pẹlu iṣesi rẹ ni, abi ifi ọwọ si i rẹ ni, o le jẹ pe ohun lo sọ ọ, abi ki o jẹ idahun si ibeere.Ati pe nigba mii, Olohun a maa gbe larubawa oko lati ọna ti o jin dide, ki o le wa bi ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - leere nipa nkankan lori awọn ọrọ ẹsin, eyi ti awọn saabe ti wọn dunni mọ ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ko ki n bi i leere, fun idi eyi, inu awọn saabe ma ndun ki larubawa oko wa bi Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - leere nipa awọn ọrọ ẹsin.Eyi, yio maa juwe fun ọ pe Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ko fi nkankan silẹ ninu ohun ti awọn eeyan ni bukaata si ninu ijọsin wọn, ati ibanilo papọ wọn, ati ṣiṣe ẹmi wọn ayafi ki o

ti ṣe alaaye rẹ, ohun ti yi o jẹ atọna rẹ nibi eyi ni ọrọ Ọlọhun ti o sọ pe:

﴿ ٱلۡيَوۡمَ أَكۡمَلۡتُ لَكُمۡ دِينَكُمۡ .. ﴿٣﴾ ﴾ [المائدة: 3]

“Ni oni, mo ti pe ẹsin yin fun yin ati pe mo si ti pari idẹkun mi le yin lori, ati pe mo si ti yọnu si Isilaamu fun yin ni ẹsin”(Al'Maa'idah 3)

Ti eyi ba rinlẹ ni ọdọ rẹ iwọ musulumi, mọ pe gbogbo ẹni ti o ba da adadaalẹ kan ninu ẹsin Ọlọhun, koda ki erongba rẹ o da, adadaalẹ rẹ yii, toun ti bi o ṣe jẹ anu, o tun jẹ ifi ẹnu aayẹ kan ẹsin Allah, Ọba Abiyi ati Ọba ti O gbọn-n-gbọn, bakannaa pipe Ọlọhun Allah ni Opurọ ni pẹlu; tori pe Ọlọhun Allah ti sọ pe:"Ni oni, mo ti pe ẹsin yin fun yin"

Nitori pe oluda adadaalẹ sinu ẹsin yii, bi igba ti o jẹ wipe ohun ti o sọ ni pe: dajudaju ẹṣin o tii pe; tori pe o ku awọn ofin (Ilana) eyi ti oun ṣe adadaalẹ rẹ, lati le fi sunmọ Ọlọhun Ọba Abiyi ti O gbọn-n-gbọn.

Ninu nkan ti o ṣeni ni eemọ julọ ni pe, ki ọmọniyan o da adadaalẹ nipa paapa Ọlọhun Allah Ọba Abiyi ti O si gbọn-n-gbọn, ati ninu awọn oruko Rẹ ati awọn iroyin Rẹ, ki iru ẹni bẹẹ o wa maa sọ pe: oun ṣe eyii lati fi gbe Ọlọhun tobi ni,

ati lati fi ṣe afọmọ Ọlọhun, ati lati fi ṣe amuṣẹ ọrọ Ọlọhun ti O sọ pe:

﴿... فَلَا تَجۡعَلُواْ لِلَّهِ أَندَادٗا وَأَنتُمۡ تَعۡلَمُونَ ٢٢﴾ [البقرة: 22]

"Ẹ ko gbọdọ mu orogun pẹlu Ọlọhun , ti ẹyin naa si mọ bẹẹ"(Al-Bakorah 22)

Iwọ na oo ṣe eemọ nibi eyi, nipa dida adadaalẹ sinu ẹsin Ọlọhun, ni eyi ti o ni ajọṣe pẹlu paapa Ọlọhun, ni eyi ti awọn ẹni isaaju ẹsin wa o ṣe rara, bakannaa awọn asiwaju (awọn alaṣẹ) na o ṣe e rara, ki iru ẹni bẹẹ o tun wa maa sọ pe: oun ni oluṣe afọmọ Ọlọhun, olugbe Ọlọhun tobi, oluṣe amulo ọrọ Ọlọhun Ọba Aleke Ọla ti O sọ pe:"Ẹ ko gbọdọ mu orogun pẹlu Ọlọhun".Ati pe ẹniti o ba yapa si eyi, olufi Olohun we ẹda ni, oluṣe afijọ Ọlọhun pẹlu ẹda ni ati ohun ti o jọ bẹẹ ninu awọn alajẹ buruku.

Bakanna yi o tun ṣe ọ ni eemọ, ki o ri awọn ti wọn da adadaalẹ si inu ẹsin ni ohun ti ko ki nṣe ara rẹ, nipa ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - wọn yio si maa pe apemọra wipe awọn ni olunifẹ ojiṣẹ Ọlọhun, ati pe awọn ni olupataki ojiṣẹ Ọlọhun (olugbe e tobi) - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ati pe ẹniti ko ba ti ṣe ikunlọwọ pẹlu wọn nibi adadaalẹ wọn yii, olubinu si ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ni iru ẹni bẹẹ, ati ohun ti o yatọ si eyi

ninu awọn alajẹ ti o buru, eleyi ti wọn yio maa fi pe iru ẹni ti ko ba ti wa pẹlu wọn nibi adadaalẹ wọn nibi ohun ti o nii ṣe pẹlu ojiṣẹ Ọlọhun.

Ninu ohun ti o tun ṣe ni leemọ ni pe iru awọn eeyan yii, nigba ti wọn nṣe adadaalẹ sinu ofin ẹsin ti ojiṣẹ Ọlọhun mu wa, ni nkan ti ko si ninu rẹ, wọn yio maa sọ pe awọn ni olugbe ojiṣẹ Ọlọhun tobi (olupataki rẹ), awọn wọnyii lai ṣe iyemeji wọn gba iwaju Ọlọhun ati ojiṣẹ rẹ, Ọlọhun Ọba si ti sọ pe:

﴿يَٰٓأَيُّهَا ٱلَّذِينَ ءَامَنُواْ لَا تُقَدِّمُواْ بَيۡنَ يَدَيِ ٱللَّهِ وَرَسُولِهِۦۖ وَٱتَّقُواْ ٱللَّهَۚ إِنَّ ٱللَّهَ سَمِيعٌ عَلِيمٞ ١﴾ [الحجرات: 1]

“Ẹyin olugbagbọ ododo, ẹ ko gbọdọ maa bẹ niwaju Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ, ẹ bẹru Ọlọhun Allah, dajudaju Olugbọ ati Olumọ ni Ọlọhun".(Al-Hujuraat)

Ẹyin ọmọ iya ẹsin: mo n bi yin leere, mo si n fi Ọlọhun bẹ yin, ati pe mo si fẹ ki idahun si ibeere na o wa lati ọkan yin, ko ki nṣe itara yin fun ẹsin, ki idahun naa o wa lati inu ohun ti ẹsin yin sọ , ko ki nṣe lati ibi mimaa kọṣe yin si awọn asaaju yin. Kini ẹ fẹ sọ nipa ẹniti o nṣe adadaalẹ sinu ẹsin Ọlọhun, ni ohun ti ko si ninu rẹ, yala ni ohun ti o jẹmọ paapa Ọlọhun ni ati awọn iroyin Rẹ ati awọn oruko Rẹ, abi Ohun ti o jẹ mọ

ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - lẹyin naa ti wọn tun wa nsọ wipe:Awọn ni olugbe Ọlọhun tobi ati ojiṣẹ Rẹ. Njẹ awọn wọnyi tọ si ki wọn jẹ olugbe Ọlọhun tobi ati ojiṣẹ Rẹ?

Abi awọn eeyan (ijọ) ti wọn o yẹ ti wọn o gbo ni ohun ti o se deede ori ọmọ-ika kuro lori ofin Ọlọhun, ti wọn nsọ pe, a gba ohun ti o wa ninu ofin Ọlọhun gbọ, a si tun gba ohun ti o sọ fun wa ni ododo, a gbọ ọ, a si tẹle e ni deede ohun ti Ọlọhun pa wa ni aṣẹ rẹ, ati ohun ti o kọ fun wa, wọn si maa nsọ pe, ohun ti shariah (Ofin) Ọlọhun o ba ti sọ, a wa kora duro kuro nibẹ, a o si nii de idi ẹ, ati pe ko tọ fun wa ki a maa gba iwaju Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ, ati pe ko tọ fun wa ki a maa sọ ohun ti kii ṣe ara ẹsin Ọlọhun sinu ẹsin Ọlọhun. Ewo ninu awọn mejeeji ni o ni ifẹ Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ lododo ati pe ewo lo nṣe titobi Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ ni ti ododo?

Ko si iyemeji nibẹ pe awọn ti wọn sọ pe a gba Ọlọhun gbọ, ati pe a gba ohun ti O sọ fun wa ni ododo, a gbọ ọ, a si tẹle ohun ti O pa wa laṣẹ rẹ, wọn tun sọ pe: a ko ara duro a si kuro patapata nibi ohun ti wọn kọ fun wa, wọn tun sọ pe: awa o to bẹẹ lati ṣe afikun si ofin Ọlọhun, ni ohun ti ko si nibẹ rara, abi ki a wa ṣe adadaalẹ sinu ẹsin Ọlọhun leyi ti kii ṣe ara rẹ. Ko si iyemeji nibẹ wipe awọn eleyi, awọn ni wọn mọ iwọn ara wọn, ti wọn si mọ pataki ẹni ti O da wọn, awọn

eyii ni wọn ṣe igbetobi Ọlọhun Ọba Aleke ọla, ati ojiṣẹ Rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - awọn eyii ni wọn fi ifẹ ododo han si Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ -ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a.

Ko ki nṣe awon oluda adadaalẹ si inu ẹsin Ọlọhun, ni ohun ti ko si nibẹ, ninu adisọkan (AQEEDAH) abi ọrọ sisọ, abi iṣẹ ṣiṣe, iwọ yio ṣe eemọ lati ara awọn ijọ kan ti wọn mọ ọrọ ojiṣẹ Ọlọhun ti o sọ pe:"O di ọwọ yin, ki ẹ jina si mimaa ṣẹda ohun ti ko ki nṣe ara ẹsin sibẹ; tori pe gbogbo idasilẹ pata adadaalẹ ni (bid'ah) ati pe gbogbo adadaalẹ pata ọna anu ni, gbogbo ọna anu, inu ina lo si nlọ".Ti wọn si mọ pe dajudaju ọrọ rẹ ti o sọ pe"Gbogbo adadaalẹ"Gbolohun ti o sọ pe "gbogbo" o ko gbogbo nkan sinu patapata, irinṣẹ ti o ko gbogbo nkan sinu ni.GbogboẸni ti o sọ gbolohun alakotan yii - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - o ni mimọ ohun ti gbolohun naa da le lori, oun ni ẹni ti o da lahọn julọ, oluṣe iṣiti fun ni julọ ni i, ko si nii sọ nkankan ayafi ki o gbero itumọ rẹ, ti o ba ri bẹẹ, a jẹ pe nigba ti Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:Gbogbo adadaalẹ pata anu niOhun ti o nsọ ye e, o si mọ itumọ ohun ti o nsọ, ọrọ yii wa lati ọdọ rẹ ki o le jẹ iṣiti ti o pe fun awọn ijọ rẹ ni.Ti awọn nkan mẹta yii ba ti le pe si ara ọrọ: Iṣiti ti o pe ati erongba, alaye ti o yanju yekeyeke, imọ pẹlu oye ti o pe, o ntumọ si pe ọrọ naa ohun ti nda le lori ni wọn gbalero. Ṣe lẹyin alaye yi, lẹyin akotan

yii, njẹ o wa tun tọ ki a pin adadaalẹ si ọna mẹta abi ọna marun bi?

Lailai, eleyi ko ni alaafia, ati wipe ohun ti apakan awọn alufaa maa npe apemọra rẹ wipe dajudaju adadaalẹ kan nbẹ ti o dara, ko le yẹ kuro nibi iṣesi meji:

Ki o ma jẹ adadaalẹ, ṣugbọn oun ro pe adadaalẹ ni i

ki o jẹ adadaalẹ, ti o si jẹ nkan ti o buru, ṣugbọn ko mọ nipa aburu rẹ

Gbogbo ohun ti wọn ba ti wa pe apemọra wipe o jẹ adadaalẹ ti o dara, idahun rẹ ni eleyii. Lori eleyii, ko si ibuwọle fun awọn aladadaalẹ lati sọ apakan ninu awọn adadaalẹ wọn di adadaalẹ ti o dara, ti ida ti o mu yi si wa lọwọ wa lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a.Gbogbo adadaalẹ pata anu niDajudaju ida ti o mu yii, wọn ṣe e ni ile-iṣẹ ijẹ Anọbi ati iranṣẹ, wọn ko ṣe e ni ile-iṣẹ eyi ti o doju ru, ṣugbọn wọn ṣe e ni awọn ile-iṣẹ ijẹ Anọbi. Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - si rọ ọ ni rirọ eyi ti o de ogongo yii, ko wa rọrun fun ẹni ti iru ida ti o mu yii wa ni ọwọ rẹ, ki ẹnikẹni wa doju kọ ọ pẹlu adadaalẹ kan, ti yio wa maa sọ wipe dajudaju adadaalẹ naa rẹwa ti ojiṣẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - si nsọ wipe:Gbogbo adadaalẹ pata anu niO wa da bi ẹni wipe mo nfura mọ wipe dajudaju

nkankan nbe ninu ẹmi yin ti nsọ pe kini ohun ti o fẹ sọ nipa alaṣẹ muumini ti nṣe Umar ọmọ Khattaab - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - ti a fi maa n ṣe kongẹ ohun ti o jẹ ootọ nigba ti o pa Ubayyi ọmọ Ka'b ati Tamiim Ad-Daari laṣẹ pe ki wọn o maa kirun fun awọn eeyan ninu Ramadan, Umar wa jade ti awọn eeyan si wa lẹniti wọn kojọ lẹyin imaamu wọn, ni o wa sọ bayi pe:Mandala adadaalẹ yii, ati wipe irun ti wọn maa nsun lẹyin igbati wọn ba ti ki i tan o lọla ju eyiti wọn dide ki lọ.Idahun lori eleyii ọna meji ni.Ọna akọkọ : oun ni wipe ko tọ fun ẹnikankan ninu awọn eniyan ki o tako ọrọ ojiṣẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - pẹlu eyikeyi ọrọ, ko gbọdọ tako o pẹlu ọrọ Abubakar, eyi ti o jẹ wipe oun ni o ni ọla ju ninu ijọ lẹyin Anọbi rẹ, tabi ọrọ Umar eyi ti o jẹ ẹnkeji ìjọ yii lẹyin Anọbi rẹ, tabi ọrọ Uthman, ẹni ti o jẹ wipe oun ni ẹnikẹta ijọ yii lẹyin Anọbi rẹ, tabi ọrọ Aliyy, ẹni ti o jẹ wipe oun ni enikerin ninu ijọ yii lẹyin Anọbi rẹ, tabi ọrọ ẹnikẹni yatọ si wọn; torí dajudadu Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga ju lọ nsọ bayi wipe :

﴿..فَلۡيَحۡذَرِ ٱلَّذِينَ يُخَالِفُونَ عَنۡ أَمۡرِهِۦٓ أَن تُصِيبَهُمۡ فِتۡنَةٌ أَوۡ يُصِيبَهُمۡ عَذَابٌ أَلِيمٌ ٦٣﴾ [النور: 63]

“ki awọn ti wọn nṣẹri kuro nibi aṣẹ rẹ, ki wọn ṣọra wọn, ki adanwo ma baa kan wọn tabi iya ẹlẹta elero”.(An-Nuur 63)

Imam Ahmad - ki Ọlọhun ba wa kẹ ẹ - sọ wipe :“Njẹ o mọ ohun ti njẹ adanwo?Adanwo naa ni imu orogun mọ ipe Ọlọhun Ọba, o ṣe e ṣe fun un ti o ba da apa kan ọrọ Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - pada, ki nkankan ninu iyẹkuro loju ọna bọ sinu ọkan rẹ, ki o si parun.O pariỌmọ Abbaas - ki Ọlọhun ba wa yọnu si awọn mejeeji - sọ pe:Yio sumọ ki okuta o maa rọ le yin lori lati sanmọ. Mo nsọ pe ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe, ẹyin si nsọ pe Abubakar ati Umar sọ pe.Ọna keji: dajudaju awa mọ ni imọ amọdaju wipe dajudaju alaṣẹ awọn muumini ti nṣe Umar ọmọ Khattaab - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - ninu ẹni ti o le koko nibi gbigbe ọrọ Ọlọhun Ọba tobi ati ọrọ ojiṣẹ Rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a. Ati pe oun si jẹ ẹni ti o gbajumọ pẹlu mimaa duro lẹnu aala Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga, titi ti o fi jẹ ẹniti wọn nroyin rẹ pe dajudaju oun jẹ olukoraro nibi ọrọ Ọlọhun Ọba ti Ọla Rẹ ga, ati pe itan arabinrin ti o tako o – ti itan naa ba ni alaafia – nipa fifi gbedeke le awọn owo ori, itan yii kii ṣe aimọ fun ọpọlọpọ, nigba arabinrin yii tako o nibi ọrọ Ọlọhun Ọba ti Ọla Rẹ ga ti o sọ pe:

﴿وَكَيْفَ تَأْخُذُونَهُۥ وَقَدْ أَفْضَىٰ بَعْضُكُمْ إِلَىٰ بَعْضٍ وَأَخَذْنَ مِنكُم مِّيثَٰقًا غَلِيظًا ۝٢١﴾ [النساء: 21]

“Ati wipe bawo ni ẹẹ ṣe gba a, ti o si jẹ wipe ni ti paapaa apa kan yin ti de ọdọ apa keji ati pe wọn si tun gba adehun ti o ni ipọn lati ọdọ yin”(An-Nisaa' 21)

Ni Umar ba jawọ kuro nibi ohun ti o gba lero nipa fifi gbedeke le awọn owo ori.Ṣugbọn itan yii, iwoye si wa nibi nini alaafia rẹ, ṣugbọn eyi ti a gba lero, oun ni ṣiṣe alaye pe, dajudaju Umar jẹ ẹniti o maa nkora duro nibi ẹnu aala Ọlọhun Ọba ti Ọla Rẹ ga, ti ko si ki nkọja rẹ, ati pe ko wa tọ si Umar - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - ti oun si jẹ ẹniti o jẹ, ki o wa yapa ọrọ olori gbogbo ẹda ti nṣe Muhammad - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ki o si wa maa sọ nipa adadaalẹ kan peMandala adadaalẹ naa.Ki adadaalẹ yii, ki o wa jẹ pe oun naa si ni eyi ti ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - gba lero pẹlu gbolohun rẹ ti o sọ peGbogbo adadaalẹ pata anu niṢugbọn ko si ibuyẹ fun wa ju wipe ki a sọ adadaalẹ (bid'ah) eyi ti Umar sọ nipa rẹ pe mandala adadaalẹ yii, ki a sọ ọ kalẹ lori adadaalẹ eyi ti ko ko si abẹ erongba Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - pẹlu gbolohun rẹ ti o sọ pe:Gbogbo adadaalẹ pata anu niTori wipe Umar - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - o njuwe pẹlu

gbolohun rẹ ti o sọ pe "mandala adadaalę yii" ó ntọka si kiko awọn eeyan jọ si ẹyin imaamu ẹyọkan lẹyin igba ti wọn ti jẹ ẹni ti o fọnka,Atipe, ipilẹ kiki irun Ramadan jẹ ohun ti o wa lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a. Atipe o fi ẹsẹ rinlẹ ninu Sọhiihu Bukhari ati Muslim, lati inu hadiithi Aaisha - ki Ọlọhun yọnu si i – pe: “Dajudaju Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - kirun fun awọn eeyan fun alẹ mẹta, o si lọra lati jade si wọn ni alẹ ẹlẹẹkẹrin, o wa sọ bayi pe:Dajudaju emi nbẹru pe ki wọn ma ṣe e ni ọranyan leyin lori ti agara o fi wa da yin lati ki i.

Imam Ahmad - ki Ọlọhun ba wa kẹ ẹ - sọ wipe :

“Njẹ o mọ ohun ti njẹ adanwo?

Adanwo naa ni imu orogun mọ ipe Ọlọhun Ọba, o ṣe e ṣe fun un ti o ba da apa kan ọrọ Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - pada, ki nkankan ninu iyẹkuro loju ọna bọ sinu ọkan rẹ, ki o si parun.

O pari

Ọmọ Abbaas - ki Ọlọhun ba wa yọnu si awọn mejeeji - sọ pe:

Yio sumọ ki okuta o maa rọ le yin lori lati sanmọ. Mo nsọ pe ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe, ẹyin si nsọ pe Abubakar ati Umar sọ pe.

Ọna keji: dajudaju awa mọ ni imọ amọdaju wipe dajudaju alaṣẹ awọn muumini ti nṣe Umar ọmọ Khattaab - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - ninu ẹni ti o le koko nibi gbigbe ọrọ Ọlọhun Ọba tobi ati ọrọ ojiṣẹ Rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a. Ati pe oun si jẹ ẹni ti o gbajumọ pẹlu mimaa duro lẹnu aala Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga, titi ti o fi jẹ ẹniti wọn nroyin rẹ pe dajudaju oun jẹ olukoraro nibi ọrọ Ọlọhun Ọba ti Ọla Rẹ ga, ati pe itan arabinrin ti o tako o – ti itan naa ba ni alaafia – nipa fifi gbedeke le awọn owo ori, itan yii kii ṣe aimọ fun ọpọlọpọ, nigba arabinrin yii tako o nibi ọrọ Ọlọhun Ọba ti Ọla Rẹ ga ti o sọ pe:

﴿وَكَيۡفَ تَأۡخُذُونَهُۥ وَقَدۡ أَفۡضَىٰ بَعۡضُكُمۡ إِلَىٰ بَعۡضٖ وَأَخَذۡنَ مِنكُم مِّيثَٰقًا غَلِيظٗا ٢١﴾ [النساء: 21]

“Ati wipe bawo ni ẹẹ ṣe gba a, ti o si jẹ wipe ni ti paapaa apa kan yin ti de ọdọ apa keji ati pe wọn si tun gba adehun ti o ni ipọn lati ọdọ yin”(An-Nisaa' 21)

Ni Umar ba jawọ kuro nibi ohun ti o gba lero nipa fifi gbedeke le awọn owo ori.

Ṣugbọn itan yii, iwoye si wa nibi nini alaafia rẹ, ṣugbọn eyi ti a gba lero, oun ni ṣiṣe alaye pe, dajudaju Umar jẹ ẹniti o maa nkora duro nibi ẹnu aala Ọlọhun Ọba ti Ọla Rẹ ga, ti ko si ki nkọja rẹ, ati pe ko wa tọ si Umar - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - ti oun si jẹ ẹniti o jẹ, ki o wa yapa ọrọ olori gbogbo ẹda ti nṣe Muhammad - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ki o si wa maa sọ nipa adadaalẹ kan pe

Mandala adadaalẹ naa.

Ki adadaalẹ yii, ki o wa jẹ pe oun naa si ni eyi ti ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - gba lero pẹlu gbolohun rẹ ti o sọ pe

Gbogbo adadaalẹ pata anu ni

Ṣugbọn ko si ibuyẹ fun wa ju wipe ki a sọ adadaalẹ (bid'ah) eyi ti Umar sọ nipa rẹ pe mandala adadaalẹ yii, ki a sọ ọ kalẹ lori adadaalẹ eyi ti ko ko si abẹ erongba Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - pẹlu gbolohun rẹ ti o sọ pe:

Gbogbo adadaalẹ pata anu ni

Tori wipe Umar - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - o njuwe pẹlu gbolohun rẹ ti o sọ pe "mandala adadaalẹ yii" ó ntọka si kiko awọn eeyan jọ si ẹyin imaamu ẹyọkan lẹyin igba ti wọn ti jẹ ẹni ti o fọnka,

Atipe, ipilẹ kiki irun Ramadan jẹ ohun ti o wa lati ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a. Atipe o fi ẹsẹ rinlẹ ninu Sọhiihu Bukhari ati Muslim, lati inu hadiithi Aaisha - ki Ọlọhun yọnu si i – pe: “Dajudaju Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - kirun fun awọn eeyan fun alẹ mẹta, o si lọra lati jade si wọn ni alẹ ẹlẹẹkẹrin, o wa sọ bayi pe:

Dajudaju emi nbẹru pe ki wọn ma ṣe e ni ọranyan leyin lori ti agara o fi wa da yin lati ki i.

Ati wipe kiki irun oru ninu Ramadan ni akojọpọ (jamaahaa) ninu sunnah ojiṣẹ ni i - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a. Ati pe Umar wa pe e ni adadaalẹ, pẹlu iwoye si pe dajudaju Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nigba ti o gbe ikirun yẹn ju silẹ, awọn eeyan bẹrẹ si ni pin yẹlẹyẹlẹ, ọkunrin kan yio dide ki i funra rẹ, ati wipe ọkunrin kan yio ki i ti ẹnikan o si wa pẹlu rẹ, ati wipe eeyan kan yio ki i ti ọkunrin meji o si wa pẹlu rẹ, ati ikọ ati akojọpọ awọn eeyan ninu mọsalasi, ni alaṣẹ awọn muumini ti nṣe Umar - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - wa wo o pẹlu iwoye rẹ ti o tọ, ti o si tọna pe ki oun ko awọn eeyan jọ si ẹyin imaamu ẹyọ kan. Iṣesi yii waye pẹlu iwoye si pe awọn eeyan ti fọnka siwaju adadaalẹ, ati pe o jẹ adadaalẹ kan ti o jẹ ti iwoye si ti o jẹ ti iṣe afiti, kii ṣe adadaalẹ pọnbele ti o jẹ ti idasilẹ kan ti Umar da a silẹ - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i - tori pe sunnah yii jẹ

nkan ti o ti wa tẹlẹ ni asiko ojiṣẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a. O jẹ sunnah ṣugbọn awọn eeyan gbe e ju silẹ lati asiko ojiṣẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - titi ti Umar fi da a pada - ki Ọlọhun ba wa yọnu si i. Pẹlu fifi oju opo yi kalẹ, ko rọrun lailai ki awọn aladadaalẹ, ki wọn wa ri abayọ latara ọrọ Umar yii fun oun ti wọn fi oju daadaa wo ninu adadaalẹ wọn.

Ati wipe, olusọrọ kan lee sọ bayi pe: Awọn nkankan nbẹ ti wọn da silẹ, ti awọn musulumi si tẹwọ gba a, ati wipe ti wọn si fi nṣe iṣẹ ṣe, ati wipe ti awọn nkan yii ko jẹ awọn nkan ti a mọ ni asiko Anọbi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - gẹgẹ bii awọn ile ẹkọ ati ṣiṣe awọn tira ati awọn nkan ti o jọ bẹẹ. Ati wipe adadaalẹ yii, awọn musulumi fi oju daadaa wo o, wọn si fi ṣe iṣẹ ṣe. Ati wipe wọn ri i pe ninu awọn iṣẹ daadaa ni o wa, bawo wa ni a ṣe fẹ ṣe akojọpọ laarin eleyi ti o fẹ jẹ wipe o jẹ ohun ifẹnuko le lori laarin gbogbo musulumi ati gbolohun asiwaju gbogbo musulumi ati Anọbi awọn musulumi ati ojiṣẹ Ọlọhun Ọba agbanla aye - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ti o sọ pe:Gbogbo adadaalẹ pata anu nildahun ni pe: ki a sọ pe eleyii ni ti ohun ti nṣẹlẹ, kii ṣẹ adadaalẹ (bid'ah), ṣugbọn eleyi jẹ atẹgun lọ sibi ohun ti a ṣe lofin. Ati wipe awọn ohun atẹgun maa nyatọ pẹlu yiyatọ awọn aaye ati asiko, ati wipe ninu awọn oju opo ti wọn ti fi

rinlẹ ni pe dajudaju awọn ohun atẹgun, o ni idajọ ohun ti a gba lero. Awọn atẹgun ohun ti a ṣe lofin, ohun ti a ṣe lofin ni oun naa, ati wipe awọn atẹgun ohun ti a ko ṣẹ lofin, oun naa kii ṣe ohun ti a ṣe lofin, bi ko ṣe wipe awọn atẹgun ohun ti o jẹ eewọ, oun naa jẹ eewọ, atipe dajudaju ti ohun ti o dara ba ti jẹ atẹgun lọ sibi ohun aburu, oun naa ti di aburu, ti a kọ ọ. Tẹti si ọrọ Ọlọhun Ọba ti O gbọn-n-gbọn, ti o sọ pe:

﴿وَلَا تَسُبُّواْ ٱلَّذِينَ يَدۡعُونَ مِن دُونِ ٱللَّهِ فَيَسُبُّواْ ٱللَّهَ عَدۡوَۢا بِغَيۡرِ عِلۡمٖۗ ١٠٨﴾ [الأنعام: 108]

“Ati wipe, ẹyin ẹ ma ṣe maa bu awọn ohun ti wọn nkepe yatọ si Ọlọhun Ọba Allah , ti awọn a wa lọ maa bu Ọlọhun Ọba Allah ni ti ikọja aaye laini imọ”.(Al-An'aam 108)

Gbogbo adadaalẹ pata anu ni

Idahun ni pe: ki a sọ pe eleyii ni ti ohun ti nṣẹlẹ, kii ṣẹ adadaalẹ (bid'ah), ṣugbọn eleyi jẹ atẹgun lọ sibi ohun ti a ṣe lofin. Ati wipe awọn ohun atẹgun maa nyatọ pẹlu yiyatọ awọn aaye ati asiko, ati wipe ninu awọn oju opo ti wọn ti fi rinlẹ ni pe dajudaju awọn ohun atẹgun, o ni idajọ ohun ti a gba lero. Awọn atẹgun ohun ti a ṣe lofin, ohun ti a ṣe lofin ni oun naa, ati wipe awọn atẹgun ohun ti a ko ṣẹ lofin, oun

naa kii ṣe ohun ti a ṣe lofin, bi ko ṣe wipe awọn atẹgun ohun ti o jẹ eewọ, oun naa jẹ eewọ, atipe dajudaju ti ohun ti o dara ba ti jẹ atẹgun lọ sibi ohun aburu, oun naa ti di aburu, ti a kọ ọ. Tẹti si ọrọ Ọlọhun Ọba ti O gbọn-n-gbọn, ti o sọ pe:

﴿وَلَا تَسُبُّوا۟ ٱلَّذِينَ يَدْعُونَ مِن دُونِ ٱللَّهِ فَيَسُبُّوا۟ ٱللَّهَ عَدْوًۢا بِغَيْرِ عِلْمٍۗ ١٠٨﴾ [الأنعام: 108]

“Ati wipe, ẹyin ẹ ma ṣe maa bu awọn ohun ti wọn nkepe yatọ si Ọlọhun Ọba Allah , ti awọn a wa lọ maa bu Ọlọhun Ọba Allah ni ti ikọja aaye laini imọ”.(Al-An'aam 108)

Atipe imaa bu Ọlọhun awọn ọṣẹbọ kii ṣe ikọja aaye bi kii ṣe wipe ẹtọ ni, atipe o si tun laaye rẹ, ṣugbọn imaa bu Ọlọhun gbogbo agbaye ikọja aala ni ko si si laaye rẹ, o si tun jẹ iṣe ọta ati abosi, fun idi eyi, nigbati o jẹ wipe imaa bu Ọlọhun awọn keferi ti o ni orinyin ninu ti jẹ okunfa lọ si ibi imaa bu Ọlọhun Ọba Adẹda, eleyi sọ ọ di eewọ ati ohun ti a kọ. Mo mu ẹri yi wa lori wipe dajudaju awọn atẹgun maa n ni idajọ awọn erongba ni. Atipe awọn ile-ẹkọ ati pipin imọ ati ṣiṣe tira, bi o ti lẹ jẹ pe adadaalẹ ni ti ko si ni igba aye Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – lori ojupọnna yi, amọ kii ṣe erongba, bi kii ṣe pe atẹgun lasan lo jẹ, atipe

awọn atẹgun si niyi wọn maa ngba idajọ ti nbẹ fun awọn erongba.

Fun idi eyi ti ẹnikan ba kọ ile-ẹkọ kan lati fi maa kọ awọn eeyan ni imọ ti o jẹ eewọ, ohun ti o kọ naa eewọ ni, ti o ba si kọ ile-ẹkọ kan lati fi maa kọ awọn eeyen ni imọ ofin ẹsin, ohun ti o kọ naa ba ofin mu.

Ti olusọrọ kan ba wa sọ pe: bawo ni o se fẹ fọ esi si gbolohun Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ti o sọ pe:Ẹniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin Islaam, yio gba ẹsan rẹ ati ẹsan ẹniti o ba ṣe e titi di ọjọ igbedide.Itumọ "SANNA" si ni "SHARAHA": iyẹn ni pe: o ṣofin.Esi ni pe: ẹniti o sọ peẸniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin IslaamOun naa lo sọ pe:Gbogbo adadaalẹ pata anu niKo wa rọrun ki gbolohun kan o wa lati ọdọ olododo ẹniti a ngba a lododo ki gbolohun mii wa pe e nirọ, ko si tun rọrun ki ọrọ ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – o tako ara wọn lailai, ko si tun rọrun ki o da lori itumọ kan pẹlu atako lailai, ẹniti o ba lero wipe ọrọ Ọlọhun ti O ga abi ọrọ ojiṣẹ Rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – tako ara wọn ki o yaa tun un wo; toripe dajudaju ero yi nwa boya latari adinku lati ọdọ rẹ, tabi latari aseeto rẹ, atipe ko rọrun ki atako o wa ninu ọrọ Ọlọhun ti O ga tabi ọrọ ojiṣẹ Rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – lailai.Ti o ba wa ri bẹ, ajẹpe alaye aisi atako

hadiith:Gbogbo adadaalẹ pata anu niFun hadiithẸniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin IslaamDajudaju Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nsọ pe:Ẹniti o ba la oju ọna sinu ẹsin IslaamAtipe awọn adadaalẹ ko si ninu Islaam, o tun wa nsọ pe: daadaaAdadaalẹ si niyi kii ṣe nkan ti o da, atipe iyatọ nbẹ nibi lila ilana ati dida adadaalẹ.

Ẹniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin Islaam, yio gba ẹsan rẹ ati ẹsan ẹniti o ba ṣe e titi di ọjọ igbedide.

Itumọ "SANNA" si ni "SHARAHA": iyẹn ni pe: o ṣofin.

Esi ni pe: ẹniti o sọ pe

Ẹniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin Islaam

Oun naa lo sọ pe:

Gbogbo adadaalẹ pata anu ni

Ko wa rọrun ki gbolohun kan o wa lati ọdọ olododo ẹniti a ngba a lododo ki gbolohun mii wa pe e nirọ, ko si tun rọrun ki ọrọ ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – o tako ara wọn lailai, ko si tun rọrun ki o da lori itumọ kan pẹlu atako lailai, ẹniti o ba lero wipe ọrọ Ọlọhun ti O ga abi ọrọ ojiṣẹ Rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – tako ara wọn ki o yaa tun un wo; toripe dajudaju ero yi nwa boya latari adinku lati ọdọ rẹ, tabi latari aseeto rẹ, atipe ko rọrun ki atako o wa

ninu ọrọ Ọlọhun ti O ga tabi ọrọ ojiṣẹ Rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – lailai.

Ti o ba wa ri bẹ, ajẹpe alaye aisi atako hadiith:

Gbogbo adadaalẹ pata anu ni

Fun hadiith

Ẹniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin Islaam

Dajudaju Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nsọ pe:

Ẹniti o ba la oju ọna sinu ẹsin Islaam

Atipe awọn adadaalẹ ko si ninu Islaam, o tun wa nsọ pe: daadaa

Adadaalẹ si niyi kii ṣe nkan ti o da, atipe iyatọ nbẹ nibi lila ilana ati dida adadaalẹ.

Idahun mii si tun nbẹ leyiti ko si laifi ninu ẹ: oun ni wipe itumọ ẹniti o ba la ilana ni pe ẹniti o ba ta ilana kan ti o ti wa nilẹ tẹlẹ ji, leyiti o jẹ wipe o ti di aisi tẹlẹ ti o wa ta a ji, lori eleyi ilana yi yio jẹ afikun ti ko kari– gẹgẹbi adadaalẹ naa se jẹ afikun ti ko kari – si ọdọ ẹniti o ta ilana kan ji lẹyin igbati wọn ti gbe e ju silẹ

Idahun kẹta mii tun wa ti okunfa hadiith yi ntọka si i, oun naa ni itan awọn ikọ kan ti wọn ko ara wọn lọ si ọdọ Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ti wọn si n bẹ ninu ipọ ti o lekoko latara ifunpinpin, Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – wa pepe sibi titọrẹ aanu fun wọn, ni arakunrin kan lati inu awọn ansọọri wa wa pẹlu igbanu kan ti fadaka wa ninu rẹ ti o sunmọ ki o wuwo ni ọwọ, o si gbe e si ọwọ ojiṣẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ni oju Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – wa bẹrẹ si n nkọ mọnamọna latari idunnu ati ayọ, o wa sọ pe:Ẹniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin Islaam, yio gba ẹsan rẹ ati ẹsan ẹniti o ba ṣe e titi di ọjọ igbedide.Nibi yi itumọ “SANNU” maa jẹ lila ọna iṣẹ ni ti ṣiṣe ti kii ṣe ṣiṣe ofin, itumọẸniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin IslaamẸniti o ba ṣẹ e lati mu u lo ti kii ṣe lati se e lofin; toripe dajudaju ṣiṣe nkan lofin eewọ niGbogbo adadaalẹ pata anu ni

Ẹniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin Islaam, yio gba ẹsan rẹ ati ẹsan ẹniti o ba ṣe e titi di ọjọ igbedide.

Nibi yi itumọ “SANNU” maa jẹ lila ọna iṣẹ ni ti ṣiṣe ti kii ṣe ṣiṣe ofin, itumọ

Ẹniti o ba la oju ọna daada kan sinu ẹsin Islaam

Ẹniti o ba ṣẹ e lati mu u lo ti kii ṣe lati se e lofin; toripe dajudaju ṣiṣe nkan lofin eewọ ni

Gbogbo adadaalẹ pata anu ni

Ki o ya lọ mọ iwọ ọmọ-iya mi wipe dajudaju imaa tẹle ofin ẹsin gẹgẹbi o ṣe wa ko lee ti fi ẹsẹ walẹ ayaafi ti iṣẹ naa ba wa ni ibamu si ofin ẹsin nibi awọn alamọri mẹfa kan:

Alakọkọ: okunfa, ti ọmọniyan ba sin Ọlọhun ni ijọsin pẹlu okunfa ti ko ba ofin ẹsin mu, adadaalẹ ti aa da pada fun ẹniti o ni i ni, apẹrẹ rẹ ni pe apakan ninu awọn eeyan maa nji ni oru ọjọ kẹtadinlọgbọn ninu osu Rajab pẹlu ẹri wipe o jẹ oru ti wọn mu ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – gun sanmọ, ki eeyan o si ji loru ijọsin ni, sugbọn nigbati wọn ti fi okunfa yi kun un o ti di adadaalẹ; toripe o ti mọ ijọsin yi lori okunfa kan ti ko fi ẹsẹ mulẹ ninu ofin ẹsin. Atipe iroyin yi – ki ijọsin o ba ofin ẹsin mu nibi okunfa – alamọri kan ti o ṣe pataki ni ti ọpọlọpọ adadaalẹ maa fi oju han latara rẹ, ninu ohun ti awọn eeyan maa nlero wipe ilana Anabi ni, ti ko si si ninu ilana Anabi.

Ẹlẹẹkeji: Iran, ko si ibuyẹ ti ijọsin o fi ni ba ofin ẹsin mu nibi iran rẹ, ti ọmọniyan kan ba sin Ọlọhun pẹlu ijọsin kan ti wọn o ṣe irun iran ijọsin naa lofin, ko nii jẹ atẹwọgba, apẹrẹ rẹ ni ki ẹnikan o pa ẹsin fun ileya, ileya rẹ o ni alaafia; toripe

o ti yapa ofin ẹsin nibi iran, atipe ileya o nii maa jẹ pipa ayaafi lati inu awọn ẹranko an’aam, awọn naa ni Rakunmi, Maalu, Aguntan/Ewurẹ.

Ẹlẹẹkẹta: Odiwọn, ti ọmọniyan kan ba ṣe alekun irun lori irun ọranyan, a a sọ pe: adadaalẹ ti a a ni tẹwọgba ni eleyi; toripe o ti yapa ofin ẹsin nibi odinwọn, ninu wipe nkan tun wa fi oju han kedere ni ki ọmọniyan o ki irun Zhuh’r lapẹrẹ ni rakaah maarun, dajudaju irun rẹ o ni alaafia pẹlu ipanupọ awọn alufa ẹsin.

Ẹlẹẹkẹrin: Ọna ti a n gba ṣe nkan, ti ẹnikan ba ṣe aluwala ti o wa bẹrẹ pẹlu fifọ ẹsẹ rẹ mejeeji, lẹyin na pipa ori rẹ, lẹyin na fifọ ọwọ rẹ mejeeji, lẹyin na oju rẹ, aa sọ pe: aluwala rẹ ti bajẹ; toripe o ti yapa ofin ẹsin nibi ọna ti a n gba ṣe nkan.

Ẹlẹẹkarun: Igba, ti ẹnikan ba pa ẹran ileya ni ọjọ akọkọ oṣu dhul-hijjah, wọn o ni tẹwọgba ileya na latari wipe o ti yapa ofin ẹsin nibi igba. Mo wa gbọ wipe apa ninu awọn eeyan maa npa agutan/ewurẹ ninu osu Ramadan lati fi ṣe ijọsin fun Ọlọhun pẹlu ohun ti wọn pa, iṣesi yi adadaalẹ ni lori ojupọnna yi; toripe ko si ohunkohun ti a le fi ṣe ijọsin fun Ọlọhun pẹlu pipa ayaafi ileya ati ẹran adaaya ati ẹran ikomọjade, amọ pipa ẹran ninu osu Ramadan pẹlu nini

adisọkan wipe ęsan nbę lori pipa nkan naa gęgębi pipa nkan ni ọdun ileya, adadaalę ni. Amọ pipa nkan latari ęran jiję, eleyi lętọ.

Ęlęękęfa: Aaye, ti ęnikan ba ko ara ro nibi ti kii şe mọşalaşi, dajudaju ikoraro rę o ni alaafia; toripe ikoraro o lee maa waye ayaafi ninu awọn mọşalaşi. Atipe ti obinrin kan ba sọ pe mo gbero lati koraro ni aaye ikirun ninu ile, ikoraro rę o ni alaafia latari wipe o ti yapa ofin ęsin nibi aaye. Atipe ninu awọn apęrę ni ki ęnikan o gbero lati rọkirika ile Ọlọhun ti o wa ri wipe aaye irọkirika ti fun, ti o si ri wipe gbogbo ohun ti o yi i ka ti fun, ti o wa bęrę si ni nrọkiraka ni ęyin mọşalaşi, irọkiraka rę o ni alaafia:

﴿وَإِذۡ بَوَّأۡنَا لِإِبۡرَٰهِيمَ مَكَانَ ٱلۡبَيۡتِ أَن لَّا تُشۡرِكۡ بِي شَيۡـٔٗا وَطَهِّرۡ بَيۡتِيَ لِلطَّآئِفِينَ ٢٦﴾ [الحج: 26]

"toripe aaye irọkiraka ile Ọlọhun gangan ni. Ọlọhun ti O ga sọ fun Ibrahim ti nşe aayo Rę pe:Ki o si tun mọ ile Mi fun awọn ti wọn o maa rọkirika rę.Suuratul Hajj, aaya: 26.

Ki o si tun mọ ile Mi fun awọn ti wọn o maa rọkirika rę .Suuratul Hajj, aaya: 26. Ijọsin o wa ni maa ję işę to daa ayaafi ti majęmu meji ba pe sibę:

Alakọkọ: imọkanga, Ẹlẹẹkeji: titẹle ilana ojiṣẹ, atipe titẹle ilana ojiṣẹ o lee mulẹ ayaafi pẹlu awọn alamọri mẹfa ti a ti sọ tan laipẹ yi.

Atipe dajudaju emi nsọ fun awọn wọnyi awọn to ṣe wipe wọn ti fi adadaalẹ ṣe adanwo fun wọn, awọn to ṣe wipe ero ọkan wọn le daa ti wọn si tun ngbero daada, to ba jẹ wipe ẹ gbero dada, awa o mọ ọna kan ti o daa to ọna ẹni isaaju – ki Ọlọhun yọnu si gbogbo wọn.

Ẹyin ọmọ-iya mi, ẹ di ilana ojiṣẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – mu pẹlu awọn eyin ọgan yin, ki ẹ si maa tọ oju ọna awọn ẹniire to saaju, ki ẹ si wa lori ohun ti wọn wa lori ẹ, ki ẹ wa wo o boya iyẹn lee ko inira kankan ba yin?

Atipe mo nsọ– ti mo si n fi Ọlọhun wa iṣọ kuro nibi ki nsọ nkan ti mi o ni imọ nipa rẹ - wipe dajudaju waa ri ọpọlọpọ ninu awọn ti wọn ni ojukokoro lori awọn adadaalẹ lẹniti maa n ṣe imẹlẹ nibi awọn alamọri ti o fi ẹsẹ rinlẹ ninu ofin ẹsin ati awọn alamọri ti ijẹ sunnah rẹ fi ẹsẹ rinlẹ, ti wọn ba ti wa yanju awọn adadaalẹ yi wọn yio daju kọ awọn sunnah ti o fi ẹsẹ rinlẹ pẹlu pipa a ti, atipe gbogbo eleyi ninu abajade awọn inira ti awọn adadaalẹ ni lori awọn ọkan ni, atipe awọn adadaalẹ inira rẹ lori awọn ọkan nkan ti o tobi ni, atipe awọn ewu rẹ lori ara nkan to buhaaya ni. Awọn ijọ

kan o si nii da adadaalẹ kan sinu ẹsin Ọlọhun ayaafi ki wọn padanu ohun ti o ṣe deede rẹ ninu sunnah tabi ohun ti o le ju u lọ, gẹgẹbi apakan ninu awọn onimimọ ti wọn saaju ṣe sọ.

Sugbọn ti ọmọniyan ba ti ni lẹmi wipe olutẹle loun pe oun o ki nṣe asofin, iyẹn a jẹ ki o maa bẹ fun un ipaya Ọlọhun ti o pe, ati idirẹbẹ ati ifaragbolẹ, ati imaa jọsin fun Ọba gbogbo agbaye, ati pipe itẹle asiwaju awọn olupaya Ọlọhun ati ọga gbogbo ojiṣẹ, ati ojiṣẹ Ọba gbogbo agbaye Muhammad – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a.

Dajudaju emi ndaju isiti mi kọ gbogbo ọmọ-iya mi to jẹ musulumi ti wọn nfi oju daada wo nkankan ninu awọn adadaalẹ boya o jẹ ohun ti o sopọ mọ paapa Ọlọhun ni, tabi orukọ Rẹ, tabi iroyin Rẹ, tabi nibi ohun ti o sopọ mọ ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ati imaa gbe e tobi, ki wọn paya Ọlọhun ki wọn si jawọ kuro nibẹ, ki wọn si mọ alamọri wọn pa lori titẹle yatọ si dida adadaalẹ, lori imọkanga yatọ si ẹbọ ṣiṣe, lori sunnah yatọ si adadaalẹ, lori ohun ti Ọlọhun Ọba Onikẹ nifẹ si yatọ si ohun ti setaani nifẹ si, atipe ki wọn woye si ohun ti yio de ba ọkan wọn ninu alaafia, ati iye, ati ifayabalẹ, ati isinmi ọkan, ati imọlẹ ti o tobi.

Mo wa nbẹ Ọlọhun ti O ga ki O ṣe wa ni olufinimọna ẹniti wọn ti mọna, ati awọn adari awọn eniire, ki O si tun tan imọlẹ si awọn ọkan pẹlu igbagbọ ati imọ, ki O si ma ṣe ohun ti a mọ ni aluba lewa lori, ki O si mu wa tọ oju-ọna awọn ẹrusin Rẹ ti wọn gba A gbọ lododo, ki O si tun ṣe wa ninu awọn aayo Rẹ awọn ti wọn paya Rẹ ati awọn ikọ Rẹ ti wọn ti jere. Ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati ọla fun Anabi wa Muhammad ati awọn ara ile rẹ ati awọn saabe rẹ lapapọ.

# تنشر الإسلام بأكثر من 100 لغة

موسوعة القرآن الكريم
QuranEnc.com
موسوعة تضم تفاسير وتراجم موثوقة لمعاني القرآن الكريم

موسوعة الأحاديث النبوية
HadeethEnc.com
موسوعة تضم ترجمات للأحاديث النبويــة وشروحها بعدة لغــات

موسوعة المصطلحات الإسلامية
TerminologyEnc.com
موسوعة تضم ترجمات المصطلحات الإسلاميــة وشروحها بعدة لغــات

منتقى
المحتوى الإسلامي
موسوعة تضم المنتقى من المحتوى الإسلامي باللغات

IslamHouse.com
مرجعيــة مجانيــة إلكترونية موثوقة للتعريف بالإســلام

جـمـعـيـة الـدعـوة وتوعية الجاليات بالربوة

جمعية خدمة المحتوى الإســلامــي باللغـــات